# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## E Ba Mi Ja Alo Yi Lati Inu Bibeli

Inu mi yio dun pupọ ti Olotu ba le gba mi laye lati fi alọ yi ṣe idaraya fun awọn ọmọ igbala ti nwọn nka Bibeli ni igbakugba, ki nwọn le sọ idahun ibiti itan alọ mi na wa ninu Bibeli.

Ni adugbo kan ti o le diẹ ni ẹgberun ibusọ koju si Iwọ-Orun Ilẹ India, o din diẹ ni ẹgbẹtala ọdun nisisiyi. Agbara odo ẹiṣan kan wa ni ilẹ na o si le koju pupọ, pẹlu ariwo ẹiṣan rẹ ferẹ le di enia l'eti gigọ bi ẹ ti mọ bi odo ti o ba nṣṣa-gbara ti i ma a pariwo ti ojo ba de.

Awọn ẹiyẹ Oṣin mẹta kan ngbe ori igi kan lẹba odo na, awọn ẹiyẹ Oṣin mẹtẹta na a si ma a fo lọ si eti Okun lati lọ wẹ nigba gbogbo nwọn a si ma a ri ẹja pajẹ ni ajẹyo ni eti Okun na.

Ni ọjọ kan, Odo-agbara na fi ibinu sọ fun awọn ẹiyẹ Oṣin yi wipe ti ẹ ba tun i pe oko yẹ ni odo ti ẹ le ma a wẹ ninu rẹ ati lati ma a pa ẹja inu rẹ jẹ, ki ẹ kuro ni agbegbe ilẹ mi, ọjọ ti ẹ ba tun lọ wẹ ati lọ pa ẹja ni eti Okun ni ẹ o jade kuro nihin pẹlu agbara. Awọn ẹiyẹ Oṣin na si fi odo-agbara na rẹrin ẹlẹya fun fifiwe ara rẹ pẹlu omi Okun.

Ẹrin yi dun Odo-agbara na tobẹtẹbẹ ti o fi pe ẹṣọ fun awọn pẹiyẹpẹiyẹ lati mu awọn ẹiyẹ, ọsin na lọ si ile onitubu kan ti o buru rekọja ala, oruko akọle iwaju ile tubu na ni:- "Ko si ojusaju ẹnikan lọdọ mi."

Bi awọn pẹiyẹpẹiyẹ na ti mu awọn ẹiyẹ ọsin na yọ si ọhun ni onitubu na ti kọ igbe wipe iru awọn ẹiyẹ wo ni ẹ mu tọ mi wa yi, ẹoyin ti ẹ mu wọn wa ni ẹ o gba iya wọn jẹ. Awọn ẹiyẹ ọsin mẹtẹta na si ke pe olu-odo-okun pẹlu ẹbẹ, Olu-Okun si ran "Kosibitinkotilegbaọmomila" si wọn. O si gba awọn ẹiyẹ Oṣin na kuro ninu Tubu o si lu awọn Pẹiyẹpẹiyẹ na ni alubọlẹ, o si fi aṣọ ẹyẹ wọ awọn ẹiyẹ Oṣin na o si fi iwe aṣẹ fun wọn ti nwọn mu lọ fun Odo agbara pe ko maṣe tun yọ awọn ẹiyẹ na lẹnu mọ lati oni lọ.

Ibiti mo are ni mo de yi o Olotu, ki awọn ti Ọlọrun ba fun ni imọ ni le dahun awọn ibere wọnyi lati inu itan alọ mi na.

Awọn ibere na niyi:-

1 Tani awọn Ẹiyẹ Oṣin mẹta na?
2 Tani awọn Odo - Agbara na?
3 Tani awọn Omi - Okun na?
4 Kini itumọ "wiwẹ ati "Ipẹjajẹ" na?
5 Tani awọn Pẹiyẹpẹiyẹ na ?
6 Tani Onitubu na?
7 Tani Kosibitinkolegbọmọmila?

Orin si ọrọ na (ohun orin "Wa ba mi gbe")

Ninu gbogbo ẹṣẹ t'iwọ o ran wa
Ko tiwa wo, ro t'awọn t'a ojẹ ẹ fun
Ro t'awọn ti ndan ninu iṣẹ Rẹ yi
Olodumare ma d'aiya fo mi mọ.
Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi,
Ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lọwọ.

Emi ni
Tinyin ninu Oluwa,
Prophet Peter A. Oyinloye.
Irorẹ Omu-Aran lẹba Ilọrin

## Itumo Alo Ogbeni Ologbon-dori-ejamu

Eyi ni itumọ alọ Ogbẹni J. A. O. Ọlọgbọn-dori-ejamu, Yaba Estate ti oṣ paapa fi ṣọwọ si wa. Eyiti o jade ninu Iwe ti 13-7/53.

[1] Ọgẹdẹ [2] Ẹmu [3] Ọkọ [4] Abẹrẹ [5] Ọfa [6] Akere Ọbẹ-kẹ ireke [7] Olu [8] Ẹyin Adiẹ [9] Igbọnẹ tabi igbẹyiya [10] Ori Aladi.

Awọn ti orukọ wọn wa ni isalẹ yi ni o fi idahun ibere na ṣọwọ si wa.

1 Ọgbẹni Rufus Ogunlimẹhin Eko, mọ mejọ, ko mọ meji yi- No. 1 ati 8.

2 Ogbeni C. Ade. Akano ti apele oruko rẹ njẹ Anu-Oluwarọ, Samrebọ G. C mọ marun - No 4, 5, 7, 9 ati 10.

3 Ogbẹni K. O. Oyedokun ti mọ marun 4, 5, 6, 7 ati 10.

4 Ọgbẹni J. T. Ade Standby, Yaba Estate mọ mẹrin 4, 5, 6, ati 7.

5 Ogbeni John Bode Fasakin, Anglican Central School, Ijoko Station mọ mẹta-No. 5, 6 ati 10.

E ku iṣẹ o.

OLOTU

## Akiyesi

Awọn ti idahun si ibere Ogbeni Mofọlọrunṣọ Ọlaonipekun, Oke Ọffa, Ibadan ti o pẹ ki o to tẹ wa lọwọ niyi.

1 J. A. Ọla. Gombe Via. Jos mọ mẹsan ko mọ mẹta No. 7 8 ati 9.

2 James Ọla Adeniran Iseyin (Ọyọ) mọ marun ati abọ pere No. 1, 2a, 3, 4, 5, ati 6.

Eyi ti a ba tun ri gba lẹhin eyi a ko ni tẹ ẹ jade mọ. E ku iṣẹ o. Ki Oluwa bukun ọgbọn ati iakaye nyin o.

OLOTU

## Aba Qlomo Yo

KISI— G. C.- Ni alẹ ọjọ Abamẹta ti iṣe ogunjọ osu kẹfa ọdun yi ni Ọlọrun fi ọmọkunrin lantilanti kan ta Ọgbẹni Jimọ Omikunle ati iyawo rẹ Wulemọtu ẹmọ ile Oluyere, Ilobu lọrẹ.

Ni ọjọ kejọ ti nwọn bi ọmọ na ni nwọn ko o jade ni ọna ti Musulumi, nwọn si sọ ọ ni Abudu Rafiu Bamidele.

Awọn enia pataki - pataki ni o peju si ibẹ lọjọ na. Baba ọmọ na si fi oriṣiriṣi onjẹ adidun, ọti oriṣiriṣi ati ọpọlọpọ siga tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun titi ilẹ ọjọ na fi ṣu. Irohin ko to amojuba ni inawo ti baba ọmọ na ṣe, o busiya o le gongo.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni awọn Ogbeni Sanusi Latunji Tailor, Olori ọmọ Ilobu, S. A. Aremu, S. A. Adeṣina Abiọla, Yesufu Akinloye, Tijani Baderinwa, A. Oyediran, S. Oyediran, S. A. Bakare (Ọffa), Raji Ajiwun (Ọffa), R. A. Jato, Lasisi Agbodọla, Kasaliyu Ayinde Olori Ọmọ Ilọn, S. Babalọla, S. Okunoye, Alfa Ayinde (Oke Odde), Alfa Sadiku (Ọyọ) ati Alfa Obadamọsi (Ọyọ).

Ki Ọlọrun da ọmọ na si, ki O ṣe e ni olori ire, ki O si fi ire kari gbogbo alabaṣeyẹ ọjọ na.




ABIYAMO ETI RE MELO?

Awọn arun wọnyi ha nyọ ọmọ rẹ lẹnu bi?

AIPERI
ORERE
INU-IWO
OSE
IGBONA
IKO
IGBE-ORIN
OTUTU
IBA
JEDIJEDI

"YARO" wa ni gbogbo ilẹ Nigeria.



## Jeki Irora Na Lo

"Metholatum" ma nmu irora kuro lara wẹrẹ bi idan.

Bi o ba ti fi pa ibi ti o ndun ẹ wẹrẹ ni yio si bẹrẹ si pa ẹtu si i. O tọrun lo gbagi lati lo Mentholatum. Sa fi pa ibi ti o ndun ẹ irora na yio si lọ. Ko si ohunkohun ti o fe ṣe ju pe ki o fi pa ibi na. Ma jafara lati lo "Mentholatum" fun anfani rẹ, o dara ju gbogbo ogun irora lọ.

TETE BO NINU IRORA







ṢE ABERE MEN-THO-LAY-TUM

Awọn the Mentholatum Co. LTD. Est. 1889 Slough, England nikan ni o nṣe e.

MENTHOLATUM


E Polowo Qja Nyin Sinu Iwe Irohin Yoruba

